**Lakaye Ọrọ**

NIGBANA ni mo wo gbogbo iṣẹ Ọlọrun, pe enia ko le ridi iṣẹ ti a nṣe labẹ orun nitoripe bi enia tilẹ gbiyanju ati wadi rẹ, sibẹsibẹ ki yio le ri i, ati pẹlupẹlu bi ọlọgbọn enia ro lati lati wadi rẹ, sibẹ ki yio le ridi rẹ.



# Irohin Yoruba

NO. 828. APRIL 19 — APRIL 25, 1961 KOBO MEJI (2D)






Dara fun Ẹjẹ Ọmọde, Agba ati Aboyun

O wa fun tita kakiri Ile-egbogi


# IJỌBA IPINLẸ IWỌ-ORUN FI AWỌN OBINRIN SI IPO ỌLA



Aworan oke yi ni ti (lati owọ osi) awọn Iyaafin M. A Ọdẹbiyi, Oloye H. I. D. Awolọwọ ati Oloye Faderera Akintọla nigbati nwọn nba awọn oṣelu wa lọ si ipade nla awọn aṣofin ilu Naijiria ti nwọn ṣe ni Lọndọnu ki Naijiria to gba ominira l'ọdun 1960.

IBADAN.

**LATI isisiyi lọ awọn obirin Ipinlẹ Iwọ-Orun Naijiria yio ma a wa ninu Igbimọ Ijọba Ibilẹ agbegbe wọn. Anfani nla yi tẹ wọn lọwọ nipa ofin kan ti Ijọba Ipinlẹ Iwọ-Orun ṣe laipẹ yi.**

Nigbati nwọn fi aba ofin na siwaju Igbimọ Aṣofin Ipinlẹ Iwọ-Orun, Minista Alakoso Iṣẹ Ijọba Ibilẹ, Alhaji D. S. Adegbenro ṣe alaye kikun nipa rẹ. Gbogbo Iṣẹ Igbimọ Ijọba Ibilẹ patapata lo kan awọn obirin ju awọn ọkunrin lọ ni ilu. Ọran to jẹmọ ọja. itọju awọn ọmọde, tita ati rira, imototo ati ibagbe alafia ni ilu jẹ awọn ọran to yẹ ki awọn obirin le ma a ba Ijọba Ibilẹ wọn mojuto.

Ijọba Ipinlẹ Iwọ-Orun gba pe, gẹgẹbi ẹda, awọn obirin ni ọgbọn ti nwọn le fi ran awọn ọkunrin lọwọ ninu iṣẹ Igbimọ Ijọba Ibilẹ. Gbogbo enia lo mọ pe rọbirọbi, ijẹkujẹ ati ilọnilọwọgba jẹ arun nla lara pupọ ninu awọn Igbimọ Ijọba Ibilẹ. Ijọba Ipinlẹ Iwọ-Orun ni igbagbọ pe ọna kan ti a le gba wo arun na san nipe ki awọn obirin wa ninu Igbimọ nitoripe oju a ma a saaba ti ọkunrin lati hu iwa ibajẹ nibiti obirin ba wa.

**IRẸJẸ NLA**

Idi pataki miran ti Ijọba fi mu ofin na wa nipe, Ijọba korira irẹnijẹ lọnakọna. Awọn obirin pọ pupọ ju awọn ọkunrin lọ ni Ipinlẹ Iwọ-Orun Ṣugbọn ninu bi ọdunrun Igbimọ Ijọba Ibilẹ to wa ni Ipinlẹ na, obirin mẹfa pere lo wa ninu Igbimọ jake-jado. Irẹjẹ nla ni eyi jẹ fun awọn obirin.

-Ijọba gba pe, lotọ awọn obirin le ma a dibo, ki a si ma a dibo yan wọn bi awọn ọkunrin sinu Igbimọ, ṣugbọn Ijọba ko gba pe o yẹ k'a fi awọn obirin sinu hilahilo "bi o ba a ki o pa a, bi o ko ba a, ki o bu u lẹsẹ" to pọ ninu ọran idibo wa nisisiyi. Nitori nkan

(Wo oju ewe kejila)

## Awọn ara Ipinlẹ Ariwa yio dibo l'oṣu ti mbọ yi

KADUNA.

IJỌBA Ipinlẹ Ariwa ṣe ikede nla kan ni ọjọ 'Ru ti iṣe ọjọ karun oṣu yi pe, nwọn ti tu Igbimọ Ijọba Ipinlẹ na ka, ati pe nwọn yio ṣe idibo titun.

Ni ọjọ Ọjọbọ ti iṣe ọjọ kẹrin oṣu karun ọdun yi ni awọn ara Ipinlẹ Ariwa na yio si lọ dibo yan awọn aṣoju wọn sinu Igbimọ titun ti nwọn yio tun ni.

Awọn ẹgbẹ mẹta: Ẹgbẹ Afẹnifẹre (Action Group) Ẹgbẹ Olomi (NPC) ati Ẹgbẹ NEPU ni nwọn jẹ pataki julọ ti nwọn si ti yan awọn ọmọ ẹgbẹ (aṣoju) wọn sita lati fi iga gba'ga ninu ibo ti nwọn fẹ di lọjọ na.

Awọn ami ibo wọn si ni igbalẹ (fun Ẹgbẹ Afẹnifẹre), ọkọ (fun Ẹgbẹ Olomi) ati irawọ (fun Ẹgbẹ NEPU).

## Ọmọ-Ọba Adeọṣun jẹ oye Agura Gbagura

ROGBODIYAN ti o ti wa nilẹ lori ọrọ oye Agura Gbagura, Abẹokuta, lẹhinti Ọba Shobẹkun Keji Agura Gbagura ana ti w'aja, pari ninu ọsẹ ti o koja yi nigbati nwọn yan Ọba Agura titun si ori oye na.

Ẹniti nwọn mu ni Agura titun na ni Ọmọ-ọba Adeọṣun.

Ọba Shobẹkun w'aja ni ọjọ Abamẹta ti iṣe ọjọ kọkandilogun oṣu kewa ọdun 1960, lati igba na si ni akata-kiti ti wa lori yiyan ọba miran s'ori oye na.

Ninu ipade awọn afọbajẹ ti nwọn ṣe gbara ti Ọba Shobẹkun ti w'aja, nwọn ṣe aṣaro nipa adele, Oloye Y. O. Lalekan, Olori Afọbajẹ ni nwọn si fi ṣe adele Ọba.

Lati igbana ni rogbodiyan ti bẹrẹ lori pe tani ọba tọsi. Olukaluku ninu awọn Ọmọ-ọba wa bẹresi yọju, ti nwọn si nfi ifẹ wọn han pe awọn nfẹ jẹ ọba na.

Ninu awọn ti nwọn kọwe si awọn Afọbajẹ ni Ọmọ-Ọba Adeọṣun ṣugbọn ko pẹ na ni a gbọ pe awọn obi Ọmọ-ọba yi kọ, nwọn ni awọn ko fẹ ki ọmọ awọn bọsi ori oye na. Eyi mu ki awọn afọbajẹ jiroro lori ẹlomiran ninu awọn ti ọba tọsi.

Lẹnupe nwọn nṣe aṣaro nipa tani awọn yio mu ni Agura ni a tun gbọ pe Ọmọ-ọba Adeọṣun ni oye na tun bọsi lọwọ.

Ki ade pe lori ,ki bata pe lẹsẹ o.

## Obirin kan bi ewele ọmọ

WINNIBA-GHANA:

IYALẸNU nla-nla ni o jẹ fun awọn oṣiṣẹ Igbẹbi Ile-iwosan Ijọba ni Winniba, Ghana nigbati abilekọ kan bi ewele ọmọ kan. Ọmọ na ni ori meji, ọwọ mẹta ati ẹsẹ meji.

Okiki irunbi yi kan kakiri Winniba ati agbegbe rẹ to bẹẹ gẹẹ ti awọn ara igun ẹrẹrin ilu fi nsare wa wo o.

Lẹhin ọsẹ kan ti nwọn si ti bi ọmọ na ni o dojubolẹ ti o si ku patapata. Ṣugbọn ohunkohun ko ṣe abiyamọ na o.

## Ẹkọ ilana nipa Haji

AWỌN Ẹgbẹ Imale kan ti oruko wọn njẹ "Muslim Association of Nigeria", yio bẹrẹ ẹkọ ilana fun awọn Musulumi ti nlọ si Mẹkka lati lọ ṣe Haji lọdun yi ni ọjọ Abamẹta ti iṣe ọjọ kejilelogun oṣu yi, nwọn yio si pari rẹ ni ọjọ keji.

Ni ile-iwe "Ansar-ud-Deen Alakoro l'Eko ni nwọn yio ṣe ipade ẹkọ ilana awọn ti yio si sọrọ

(Wo oju ewe kejila)

# IWA YI KO DARA: IRỌ KO YẸ ỌMỌLUWABI

## OLOYE ADEYI SỌ OTITỌ FUN FANI-KAYỌDE

IBADAN.

NI ọjọ Aje ti iṣe ọjọ kẹwa oṣu yi, Minista Alamojuto Eto Owo ati Iṣẹ Ọwọ ni Ipinlẹ Iwọ Orun, Oloye A. O. Adeyi ku eru eke le Olori Ẹgbẹ Alatako lori fun ọrọ ibanijẹ ti o sọ ninu Igbimọ Aṣofin Ipinlẹ Iwọrun ni ọjọ Ẹti ti iṣe ọjọ keje oṣu kanna. Eyi ni ẹkunrẹrẹ ọrọ ti Oloye Adeyi sọ ninu Igbimọ Aṣofin na:—

"Ọrọ ti Olori Ẹgbẹ Alatako sọ ni ọjọ Ẹti to kọja yio wa ni iranti titi aiye gẹgẹ bi ọkan pataki ninu awọn ọrọ janduku tị ẹnikan ninu ipo ọla bi tirẹ ninu Igbimọ Aṣofin ni agbaiye koi ti sọ ri.

### ỌRỌ ALUFANṢA

"Nigbati o ma a pari ọrọ alufanṣa rẹ, o sọ lokunkundun pe afẹku ti ba owo bi adọta ọkẹ pọnun ninu owo Igbimọ ti ngmojuto tita koko, o si sọ siwaju si pe awọn "enia ja-nkan-ja-nkan ninu Ẹgbẹ Afẹnifẹre (Action Group)" lo raganbu owo na, ati pe Ijọba si fi ọwọ pa wọn lori.

"Ninu Igbimọ Aṣofin bi tiwa nihin, awa ko le yọda fun enia lati lo anfani aye rẹ lati fi abuku kan ẹnikan bẹni awa ko si fẹ ki ẹnikẹni lo aye rẹ l'ọna to lodi si ohun ti iṣe otitọ ati iwarere. Nitorina ko si enia gidi kan ti yio lo anfani aye rẹ ninu Igbimọ Aṣofin yi lati sọ ọrọ ti o mọ pe on ko le sọ nibomiran laifi ara rẹ sinu ewu ẹjọ fun abuku si Ijọba ati ibanilorukọjẹ.

"Iwa Olori Ẹgbẹ Alatako nihin ko wọ ẹgbẹ rara, o si jẹ iwa ojo lati ma a fi abuku ati ẹgan kan Ijọba ati awọn olotu rẹ laisi ni ẹtọ fun ṣiṣe bẹ.

### IRỌ NI, EKE SI NI

"Irọ ni Olori Ẹgbẹ Alatako pa; eke ni o ṣe, ọrọ ti oju rẹ ko to ni eyi ti o sọ pe afẹku ti ba owo bi adọta ọkẹ pọnun ninu owo Igbimọ ti ngmojuto tita Koko. Irọ patapata ni gbogbo rẹ.

"Otitọ to wa ninu ọran na nipe, kọbọ kan ko sọnu ninu owo Igbimọ na. Boya Olori Ẹgbẹ Alatako ti gba ọna ti ko tọ gbọ irohin nipa iwadi ti Ijọba fẹ ṣe, ati pe o si fẹ lo irohin na ni ọna ti o ro pe on yio fi gba iyi, ti on yio si fi abuku kan Ijọba. Eyi ko yẹ ẹni abire. Ki iṣe iwa to yẹ ẹniti o wa ni ipo ọla.

"Alaga, mo fẹ fi anfani yi kẹwọ lati sọ okodoro otitọ to wa ninu ọrọ na ninu Igbimọ yi. Nigbati a npero lati din owo Koko, o han siwa pe o yẹ ki a mọ iye tọnnu koko to wa lọwọ awọn to nra koko fun Igbimọ ti ngmojuto tita koko. O yẹ ki a mọ iye tọnnu koko to wa lọwọ wọn ki o to di pe a ṣe ikede nipa ẹdinwo koko.

"Ọjọ diẹ ṣaju ẹdinwo na, mo fun awọn oṣiṣẹ Igbimọ ti ngmojuto tita koko laṣẹ lati ṣe ayẹwo kakiri, ki nwọn si mọ iye tọnnu koko ti o wa lọwọ olukuluku awọn ti nra koko fun Igbimọ na. Awọn oṣiṣẹ na ṣe iṣẹ wọn daradara laimu awọn agbẹ onikoko fura pe boya owo koko le din: awọn oṣiṣẹ paapa ko tilẹ mọ nipa ẹdinwo na.



OLOYE A. O. ADEYI

* * * *

### ENIA ṢORO

"Ni ọjọ na gan ti owo koko din, awa mọ iye koko to wa lọwọ awọn ti nra koko fun Igbimọ na. Ẹtọ nipe ki Igbimọ na san iye owo ti o ti nsan tẹlẹ fun iye tọnnu koko to wa lọwọ awọn tị nra koko fun un. Ṣugbọn gbogbo wa mọ pe, enia ṣoro, awọn miran le bumọ iye tọnnu ti nwọn ni.

Iṣẹ ti Igbimọ tị ngmojuto tita koko nipe ki o wadi ohun gbogbo daradara, ki o si mọ otitọ nipa iye tọnnu koko to wa lọwọ olukuluku wọn. Nipa iriri iṣẹ oṣoṣu pẹlu wọn, Igbimọ na ni oye bi koko wọn ti pọ to. Ṣugbọn iye tọnnu koko ti nwọn sọ pe o wa lọwọ wọn pọ tobẹ ti Igbimọ na fi fura pe "irẹ run".

"Nwọn mu ọran na wa si etigbọ mi gẹgẹbi Minista ti ngmojuto ọran Igbimọ na, emi si paṣẹ pe nwọn ko gbọdọ san owo fun ẹnikẹni lori iye tọnnu koko to ba ru wọn loju titi nwọn yio fi gbọ aṣẹ lati ẹnu mi.

"Lodi si ọrọ ibajẹ ti Olori Ẹgbẹ Alatako sọ nihin, awa koi tị fun Igbimọ na laṣẹ lati san owo, Igbimọ na koi ti san owo kọkan.

### ETO NIPA IWADI

"Lẹhin ti mo ti ba Alakoso Ijọba ṣaṣaro pọ, mo pinnu lati yan ikọ iwadi fun gbogbo ọran na. Pẹlu adehun Alakoso Ijọba, mo bẹ Adajọ-Agba lati fun mi ni oṣiṣẹ pataki kan ti yio ṣe iwadi na. Adajọ-Agba ti darukọ ẹniti yio ṣe iwadi na: laipẹ iwadi na yio si bẹrẹ.

"Ki Igbimọ Aṣofin to bẹrẹ ipade yi li a ti pinnu lati ṣe iwadi na, ipinnu na ko si ni nkankan ṣe pẹlu ọrọ rirun ti Olori Ẹgbẹ Alatako sọ nihin. Mo ro pe Olori Ẹgbẹ Alatako ti gbọ nipa ikọ iwadi na, o si fẹ lo ọran na lọna madaru lati gba iyi. Mo sọ, mo tun sọ ọ pe, irọ patapata ni olori Ẹgbẹ Alatako pa, eke ni Olori Ẹgbẹ Alatako ṣe nigbati o sọ pe afẹku ti ba owo bi adọta ọkẹ pọnun ninu owo Igbimọ ti ngmojuto tita koko. Mo tun sọ pe, a koi ti i san kọbọ fun awọn ti nra koko fun Igbimọ na.

"Mo fẹ ki Olori Ẹgbẹ Alatako darukọ ẹnikan ti Igbimọ na fun ni owo ninu awọn tị iye tọnnu koko won ni ariyanjiyan. Bi Olori Ẹgbẹ Alatako ba jẹ ẹni ọla, o yẹ ki o le jẹri toto si isokuso ti o sọ, tabi ki o ko gbogbo ọrọ rẹ jẹ, ki o si tọrọ aforiji.

"Fun gbigbọ ati mimọ awọn aṣoju ninu Igbimọ Aṣofin yi, mo fẹ sọ pe losọọsẹ ni Igbimọ ti ngmojuto tita koko mọ iye tọnnu koko ti o wa ninu aka awon ti nra koko. Nipa eyi, Igbimọ na mọ iye tọnnu koko ti olukuluku ni.

Lakoko ti owo koko fẹ lọ silẹ, awọn oṣiṣẹ Igbimọ na

(Wo oju ewe keje)

PALM LINE

wa fun iṣẹ rẹ





FUN kiko orișiriṣe ọja wọlu ti enia ni lati ma a lo lojojumọ lọ si idi irinṣẹ ohun ẹgbin ati ti ẹrọ, awọn ọkọ Palm Line titun ni o yaaju fun iru iṣẹ bẹẹ nipa titete ṣee ati ṣiṣe dada nigbakugba. Ẹrukẹru ti o ba ti ni fifi ọkọ ko Palm Line ni gbogbo irinṣẹ ti o yẹ fun un, – o si wa fun iṣẹ rẹ nigbakugba.

Iṣẹ wa ni lati ma a ko gbogbo ẹru nyin

Ko o wa fun PALM LINE

## ỌRỌ AKEWI : Lati ọwọ ỌMỌ-ỌBA AKIBU ALARAPE, IBADAN

# ALUBARIKA L'OJU (13)

OLOTU Iwe "Irohin Yoruba", karaole o. Gẹgẹbi asọti ọrọ wa ni ọsẹ ti o kọja, lẹhin ti ọkọ awọn ọmọde na ti fọ si meji ti olukaluku wọn si gba ọna tirẹ lọ, awọn mejeji si lọ gunlẹ si ebute ọtọọtọ bakanna.

Nigbati ẹnikini gunlẹ si ebute tirẹ, o ba ọpọlọpọ awọn enia ni ebute na ti nwọn nwẹ, awọn enia na si jẹ awọn iranṣẹ ọba ti n[illegible]n ko awọn ẹṣin wa si o[illegible] ti fọ.

Nwọn si bi ọmọde yi lere wipe, "nibo ni o ti mbọ? Ọmọ na si sọ fun wipe, ilu awọn jinna, ati pe, nṣe ni ọkọ ti nwọn wọ ṣe ijamba loju omi ti olukaluku awọn ko si ri ara awọn mọ.

### IRANṢẸ ỌBA

Ni kukuru, bayi ni awọn iranṣẹ ọba na ba fi mu ọmọ na lọ si ile, o si mba wọn gbe ninu Afin Ọba, Ọba ko si mọ wipe, ọmọ yi wa nibẹ.

Lẹhin nkan bi oṣu mẹfa ti ọmọ yi ti wa ni Afin Ọba, bẹni ọmọ keji na si tun gunlẹ si ebute ibomiran ti o si jinna to nkan bi ogoji ibusọ si ilu Ọba yi.

Ọmọ yi si wa ni erekuṣu ti ọkọ rẹ gunlẹ si na fun nkan bi oṣu mẹta, lẹhin-na ni o wa bẹrẹsi gbọ irohin wipe, Ọba kan wa ni ilu kan ti o fẹran ajoji pupọ, atipe, ko tilẹ si ohunkohun ti enia le wa de ilu na ti oluwarẹ rẹ ko ni ri i, ilu na tilẹ dara pupọ.

Nigbati ọmọ yi bẹrẹsi gbọ irohin ilu yi, o si pinnu lati lọ ṣe ibẹwo ilu na.Bayi ni ọmọde yi ba gberasọ ti o si forile ọna ilu nla yi ni owurọ ọjọ kan.

Ọmọ yi rin titi ti ilẹ ọjọ kini fi ṣu, o si sun si idi igi nla kan bayi, bi ilẹ ọjọ keji si ti ngmọ ni ọmọ yi tun bẹrẹ irin-ajo rẹ bakanna, o si wọ ilu na ni irọlẹ ọjọ keji na, o wa kọrisi ọna ile Ọba taara.

### AFIN ỌBA

Nigbati o de inu Afin Ọba, o sọ fun wọn nibẹ pe ajoji ni on ni ilu yi, on ko si mọ ẹnikẹni ni ilu na, ṣugbọn on ti gbọ irohin wipe ilu na dara pupọ, nitorina, nkan ti on nfẹ ni pe ki on ma a ba wọn gbe gẹgẹbi ọmọ-ọdọ fun Ọba.

Olori iranṣẹ Ọba si mu ọmọ na lọ si iwaju Ọba, o si sọ fun Ọba gẹgẹbi ọmọ na ti wi. Ọba si gba bẹ ẹ.

Bayi n, awọn ọmọde mejeji yi ti ṣe wa ni Afin Ọba ti nwọn ko si mọ ara wọn, Ọba paapa ko si mọ wọn rara. Ṣugbọn nigbati Ọba na ba ranti iya rẹ ati awọn aburo rẹ mejeji, nṣe ni ara rẹ ma a nrẹwẹsi ni akoko na; ti ko si ni idaraya.

Irẹwẹsi na pọ to bẹ ẹ gẹ ẹ ti awọn Asunmọba fi bẹrẹsi bere lọwọ rẹ pe "Kabiyesi; ṣe ko si nkan bayi o?" O si nfun wọn lesi bayi pe, "ko si kinikan o, ẹnyin enia wa, nṣe ni mo kan tilẹ nronu wipe, bawo ni gbogbo nkan na tilẹ ti nlọ si lode aiye wa isisiyi? Ero yi ni o si ma a ngmu aarẹ ọkan ba mi lẹkọọkan. Nitorina, ko si kinikan o, ẹnyin enia wa."

### IYA WỌN GUNLẸ

Bayi ni gbogbo nkan na si nlọ deede, ti Ọba na si ngbadun aiye rẹ lọ, ti awọn ọmọde mejeji na si wa ni Afin Ọba laimọ ara wọn nitoripe, nwọn ko fi awọn mejeji si ibugbe kanna rara, ṣugbọn labẹ asia Ọba yi kanna ni nwọn wa.

Mo ro wipe ẹnyin onkawe wa ko ni gbagbe wipe, ọkọ ti iyawo na, ti iṣe iya awọn ọmọ na wa ninu rẹ, ni o gunlẹ gbẹhin patapata, atipe, larin aginju igbo nla kan bayi ni abala ọkọ na gunlẹ si, ti iya wọn na si bọsi ori ilẹ ni alafia, o si wo ọtun, ọ wo osi, ko ri ẹnikẹni.

Lẹhin ti iya yi ti duro fun igba diẹ nibiti o gbe gunlẹ si na, ni o wa ṣe akiyesi pe, nṣe ni o dabi-ẹnipe, eefin kan nru ni



AKIBU ALARAPE

* * *

ọkankan, iya yi si bẹrẹsi ro wipe, "tani o ha ndana ni ọkankan lọhun ngni? Tabi enia kan ngbe iha-ihin ni bi?

Iya yi si fi ori le ọna ọkankan ibẹ, nigbati o ku diẹ ki o de ibẹ ni o ba da ṣọbori nitoripe Ẹlẹha ni obirin na latilẹwa.

Nigbati o de ibi ina yi o ba baba kan nibẹ pẹlu kẹkẹ-ẹlẹṣin kan ati awọn ẹṣin nlanla meji ti baba na fi nfa kẹkẹ na lọ si irin-ajo rẹ.

Baba na si bẹrẹsi ki Ẹlẹha yi wipe, "ẹ ma a wolẹ o, ẹ ma a rọra o, ẹ nlẹ o, ẹ ma a wolẹ o," Ẹlẹha na si nda a lohun wipe, "Ẹ ku irin o, ẹ ku irin o."

Olotu, a dupẹ o.
Ọmọ-ọba nrele o.
O digba.




## Owe Ilẹ Yoruba

### (Lati ọwọ L. Ade King, Ilesha)

ABIYAMỌ ọta agan, ẹni nṣiṣẹ ọta ọlẹ.

Agbajata to fowo ra ọbọ, iṣẹ wo ni ọbọ leṣe ti aja ko le ṣe?

Bi a ba bọju, ti a mọnu, agbọn la npari rẹ si.

Ojo ko ba ẹnikan ṣọrẹ, ẹni eji ri leji npa.

Agbọ-igbọ tan ede a ma a da ija silẹ.

Alai nitiju to lọ si ile aya rẹ lọ ku si.

Bi ekute pe igba ologbo ni nṣe ọkọ wọn.

Adiẹ jẹ agbado o ni on ko ni ẹhin, kini awọn ti o ni ehin tun njẹ?

Aimọ ete m'ero ni ngmu ọmọ iya meji ku s'oko ẹgbẹfa.

Ẹniti o se ọbẹ aidun a ni ki ẹbọra pa a, ẹniti ko se rara nkọ?

Bi alẹ ba lẹ, a fi ọmọ ayo f'ayo.

A fi atẹwọ fọn ina ki i r'odo.

Aini ọra Ogongo a ko le fi we ti Adigbọnranku.

Aito odo tọsi to wipe olodo diju kọnkọ diju.

Ebi npa mi ko ṣe fi ife wi.

Gọgọ ti nka obi, ti o nka awusa, ọjọ ti o ba ka odi ẹyin ni yio ya.

Gba a! gba a!! gba a!!! ni ẹrin iyawo nigbati ọkọ rẹ ba ṣẹṣẹ gba owo oṣu.

Hara-huru irawe ninu ẹẹrun, ọjọ ti ojo ba rọ ni yio pin.

Jaguda paali baba bilisi, agidi paali baba ọmọ kọmọ.

Alaibikita enia lo nfọ ile oye de'lẹ, ọmọ rere ni i tun ile baba ṣe.

A gbe arọ gun ẹṣin, o nkan saara, o gbagbe pe, funra ara on kọ ni on gun un.

Ani afọnu ni ọ, o mbọ ewu ija, tani sọ pe o ko le ja.

# KADARA ẸDA (16)

## KINI OHUN TI O WA NINU AWỌN EEWỌ ATI OFIN ATỌWỌ-DỌWỌ ORILẸ-EDE ?

KOSI ọna ti a le gba ṣe alaye kikun lori kadara ẹda l'aifi ẹnu kan awọn orişirişi ofin ati igbagbọ atọwọdọwọ pẹlu awọn ohun ti a ka si eewọ ni orilẹ ede wa ati awọn orilẹ ede miran.

Biotilẹjẹpe iba diẹ ni awọn enia ti o ka iru awọn ohun eewọ ati ofin atọwọdọwọ wọnyi si tabi ti nwọn ni igbagbọ ninu wọn, sibẹsibẹ nwọn jasi ara igbesi aiye wa eyiti ko şai kan ẹnikọọkan wa lọna kan tabi omiran.

Onikaluku orilẹ ede kakiri gbogbo agbaiye l'o ni ẹgbẹgbẹrun awọn ofin atọwọdọwọ wọnyi, a si le ri ogunlọgọ awọn enia nlanla orilẹ ede kọọkan ti nwọn nbọwọ fun awọn eewọ na.

**(Lati ọwọ M. A. Akinbọade, Ibadan)**

### ABẸ AKASỌ

Ni ilu Amẹrika, şaşa enia ni a le ri ti yio se aşişe lati kọja ni abẹ akasọ. Ọpolopo awọn Geesi, India,



M. A. AKINBỌADE

* * *

ati orişirişi ara orilẹ ede awọn enia funfun miran paapa nşami si eyi.

Ọkan ninu alaye ti a gbọ nipa eyi ni wipe akasọ ti a ba gbe ti ogiri jasi ohun ti a fi ngun oke, şugbọn a ko le gba abẹ akasọ na goke bikoşe ki a gun un lati ode.

Nitorina, igbagbọ awọn enia ni wipe bi enia kan ba gba abẹ akaso kọja oluwarẹ ko ni le "dide" borọborọ. Eyini ni pe ko ni le tete jẹ ohun ti o fẹ jẹ ni aiye.

Awọn miran si tilẹ sọ wipe kiakia ni işẹlẹ buburu ma a ntẹle aşişe yi.

### OFIN ATI EEWỌ

Gẹgẹbi a ti şakiyesi, awọn ofin atọwọdọwọ wọnyi pọ pupọ, nwọn si ya si orişirişi ọna. Lati ibi wipe a ko gbọdọ şe bayi,— bi a ba şe bẹ ẹ nkan bayi ni yio şẹlẹ titi lọ de ibi wipe bi a ba nfi iru oruka egbogi (Talisman) kan si ọwọ wa tabi bi a ba nlo iru işora bayi-bayi agbara ajẹ tabi oloogun kan ko ni ka wa.

Gẹgẹbi iriri mi bi mo ti nşe iwadi nipa ẹkọ kikọ lori awọn nkan ijinlẹ, mo kiyesi i daju wipe ko si orilẹ ede kan ni gbogbo agbaiye ti ko ni iru ofin ati awọn eewọ wọnyi ti nwọn nteriba fun.

Bakanna ni ko si orilẹ ede ti ko ni iru egbogi (oogun)tirẹ ni orişirişi.

### BIBORI IŞORO WA

Ohun ti mo mọ daju ni pe kosi enia ti o le ka gbogbo awọn eewọ yi si tan; kikasi ati şişe ami wọn to fun işẹ igbesi aiye enia l'aişe ohunkohun miran pẹlu rẹ.

Sibẹsibẹ na, a nilati ranti wipe iba diẹ kinun ni a le gba wipe o ni apẹrẹ ti o le şe e gbagbọ ninu awọn ofin abalaiye wọnyi.

L'aişe aniani, ọpọlọpọ ninu ohun ti a kọ lati gbagbọ nitori oju lila, ẹkọ kikọ tabi ẹsin sisin ni o ni itumọ ti o si ni apẹrẹ ti o daju lori kadara wa.

Boya a ki ba ti şe wahala lati şe ayẹwo awọn nkan wọnyi biko ba şe wipe ọpọlọpọ ninu awọn ohun ti a ko kasi wọnyi l'o jasi kọkọrọ ti o nşi ilẹkun fun ni nigba miran lati bọ ninu işoro wa.

### AKIYESI ARA

Ngo tubọ şe alaye siwaju si i lori eyi bi a ti nba ọrọ wa bọ yi.

Awọn alaye mi wọnyi ki i şe lati gbin in si ọkan ẹnikẹni pe dandan ni o yẹ ki a ma a şami awọn eewọ ati ofin atọwọdọwọ wọnyi, emi paapa jẹ ẹnikan ti o lora pupọ lati gba eyikeyi gbọ ninu wọn.

Şugbọn nigbati a ba ko gbogbo kaadi na sori tabili ti a si şe ayẹwo rẹ finifini, boya a o ri eyiti o le şe ni ni anfani kekere ninu wọn nipa akiyes'ara.

A o tun ma a pade o. Alafia fun nyin.

# Alọ o? Alọ!

EKINI—A pe oku o dahun, a pe alaye ko le fọhun.

EKEJI—Ẹbiti babalua mi kan lailai, ẹbiti babalua mi kan laelae, bi o re siwaju a pa ogun, bi o re s'ẹhin a pa ọgbọn, bi o re lagbedemi a pa adọta.

ẸKẸTA—Baba agbenugbodagba jẹ ọlogbọn, baba agbenugbo dagba jẹ oloye, şugbọn kò ni ọgbọn tabi oye lati fi rin ibusọ kan ni wakati kan.

ẸKẸRIN—Ojo rọ-rọ-rọ ko de ile Olumọta, Olumọta ti ni omi tirẹ tẹlẹ ki ojo to rọ.

ẸKARUN—Ọgẹdẹ ni omi ninu, o tun nkigbe orungbẹ.

ẸKẸFA—Rukuruku kẹtan, oku na tun kẹtan.

EKEJE—Aiye ti Binti njẹ, ọba ilu kan ko ri i jẹ.

ẸKẸJỌ—A si idi iroko, a ba igba ẹyin.

ẸKẸSAN—Ọna Baba-alọ kan lailai ọna Baba-alọ kan laelae, ara aiye ki i rin, ero ọrun ki i gba ibẹ, o si ndan gbinrin.

ẸKẸWA—Igba gende sun, a ko mọ ẹniti o kangun.

IKỌKANLA—Laiye ogun rẹfurẹfu, nigba ogun rẹfurẹfu, nigbati ogun buru tan igba gende ni o sare wọ inu ado kan lọ sapamọ

## ITUMỌ ALỌ

Ekini—Ewe gbigbẹ.

Ekeji—Ọlọ-ata

Ẹkẹta—Ijapa

Ẹkẹrin—Omi inu agbọn

Ẹkarun—Ẹnu

Ẹkẹfa—Ẹşin ati ẹniti o gẹşin

Ekeje— Jiga

Ẹkẹjọ—Ẹpa

Ẹkẹsan—Abonu Ọka

Ẹkẹwa—Ọşan ilu

Ikọkanla—Ẹyọ Atarẹ.




O NJẸKI NGNI AGBARA ATI ILERA

NI NAIJIRIA NI A TI ŞE AMAMA

AWỌN ALAGBATA RẸ NI: GLAXO—ALLENBURYS (NIGERIA) LTD. P. M. B. 2310, LAGOS, ati pẹlu ni ABA ati KANO.

